# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

NO 872 TUESDAY DECEMBER 15, 1964 (2D)


## Awọn Serafu Ngbadura Fun Alafia

EKO Ni deede agogo marun irọlẹ ana ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi ni gbogbo awọn Serafu ijọ aladura ti nwọn wa ni Eko ati agbegbe rẹ parojọ si gbangba ode L'Eko ti gbogbo wọn si gba akanṣe adura pataki fun awọn aṣiwaju oṣelu wa gbogbo.

Onirohin wa Ejongboro ti o lọ sibi isin adura na ni irọlẹ ana fi ye wa wipe o to ọkẹ meji (40, 000) enia ti gbogbo wọn wa ninu aṣọ fun ẹwu funfun, fila funfun, bata funfun ti gbogo wọn si funfun balau. Ọkan ninu awọn "Woli" ti o wa nibẹ ni alẹ ana ṣe alaye fun Ejongboro wipe, ọjọ meji ni awọn yio fi ṣe adura pataki na. O tun ṣe alaye pe pẹlu Aawẹ ni awọn yio gbadura na fun ọjọ meje laiko fi ẹnu kan omi tabi ata ki gbogbo rogbodiyan ti o wa larin ilu wọnyi ki o le lọ silẹ.

Nwọn si tun kesi gbogbo awọn aladura ti ko ti gbọ pe ki wọn maṣe alaiko wa si ipade adura na ni gbangba ọdnu L'eko. Ki Oluwa ki o gbọ adura gbogbo wa o.

## Dokita Okpara Sọ Pe:

# AKINTỌLA KO FẸ KI ILẸ IGBOMINA GBA OMINIRA

**OGOJA: Gbogbo enia lo ya ẹnu silẹ ti nwọn fẹrẹ le ma pade mọ nigbati Dokita Mickeal Okpara Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria, ati olori ẹgbẹ Alakukọ, nsọ fun gbogbo awọn enia ti nwon wa gbọ ọrọ rẹ pe, Oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ati olori ẹgbẹ Dẹmọ ni ko fẹ ki awọn enia Ilorin ati Kabba Igbomina kuro ni abẹ Ipinlẹ Ariwa, ti o si nwa ọna bi nwon o ti ṣe ma ṣe ẹru awon enia lailai** ta Okpara ti ti iṣe Alakoso Ijọba laiko ṣe iyemeji.

Dọkita Okpara tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ wipe Adehun ikọkọ kan wa larin Oloye Akintọla ati Alhaji Ahmadu Bello, wipe ki Awọn enia Ilorin ati agbegbe Kabba ki nwọn o ma le kuro labẹ Ipinlẹ Ariwa.

Dokita Okpara tun fi han gbogba enia wipe ifẹ inu awọn enia Ilorin ati agbegbe Kabba ni lati wa derapọ mọ awọn Yoruba ọmọ Iya wọn ni Ipiulẹ Iwọ Orun Naijiria.

Bi awọn enia Ilorin ti iṣe Ilẹ Igbomina ati ti agbegbe Kabba ti nle lọsan ati loru to wipe awọn fẹ papọ mọ awọn ọmọ Iya awọn Oloye Akintọla kọ eti ikun si igbe awọn enia na.

O tilẹ tun sọ gbangba pẹ lu igboiya loju gbogbo awọn enia na pe, "Adehun ikọkọ to wa larin Sardauna ilẹ Sokoto ati Oloye Akintọla ko jẹki Akintọla o fẹ ki awọn enia na o pada si ọdọ Yoruba ọmọ iya wọn"

Dọkita Okpara tun fi kun ọrọ rẹ pe, "Gẹgẹbi iwa arekereke Oloye Akintọla o ti gba lati sika adehun na ni tori ileri asan ati ala ti ko le ṣẹ ti Ahmadu Bello nṣe fun un"

O tun fi han awọn enia na pẹlu idaniloju wipe "Lasiko to jẹ wipe, awọn enia awọn ẹmewa rẹ kuro lori aga akoso Ijọba ni asiko ibo, alafia, ati ifọkanbalẹ ati ilọsiwaju ko ni le pada si Ipinlẹ Iwọ Orun

!!AṢIRI IKỌKỌ!!

Nipari ọrọ rẹ Dọkita Okpara wa kesi Oloye Akintọla, pe !!Majẹki a gbọ irọ nibẹ. Bi o ba jẹ wipe, irọ ni gbogbo ọrọ ti mo nsọ yi, ki Oloye Akintọla yara sọ, fun gbogbo aiye gbọ. Mo ṣetan lati tu aṣiri ikọkọ na fun gbogbo enia!!

Ninu ọrọ ti awọn enia ilu Bansarra ni agbegbe Ogoja sọ, nwọn fi nye Dọkita Okpra wipe, gbọnin-gbọnin ni awọn duro lẹhin rẹ ati Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

Nwọn wa fi ye Dọkita Okpara ki o to lọ kuro ni ọdọ wọn pe, awọn ni ojulowo igbẹkẹle ninu Ijọba rẹ, awọn si nṣe olotitọ to Dọki-



**Dokita M. I. Okpara**

Olori Ẹgbẹ Alakukọ

N w ọ n wa fun Dọkita Okpara ni ọkan balẹ, pe ki o ma a woran. ki o si ṣe akiyesi ohun ti yio ṣelẹ ninu ibo ti mbọ yi.

Dokita Okpara ṣe afikun ninu ọrọ rẹ wipe ko si otitọ ninu ọrọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi (N. P. C.) nsọ kakiri wipe, awọn nfẹ isọkan on irẹpọ awọn enia orilẹ ede Naijiria.

Onirohin wa kan ran wa leti pe, o ti le ni ọdun meji nisisiyi ti awọn ọmọ Ilẹ Igbomina ti nja lati gba ominira, ki awọn enia na o si le daduro gedegbe lati maa da Ijọba ara wọn ṣe.

A gbo wipe awọn enia na ti ran aṣoju wọn lo si Kaduna lasiko ni iye igba lati lọ bu wọn ṣe daduro lati ma a ṣe ijọba ara wọn.

Ṣugbọn lati igbati nwọn ti nṣe wahala na ko si eyiti o ti yori si rere oniwe irohin lo si Ile ọlan ninu awọn ọmọ Ile Igbomina Ile Ọlọla Ọlanrewaju ti iṣe Minista Alamojuto eto iṣe awọn Ọlọpa fun Apapọ Ijọba lara lati gbọ bi ọrọ ilẹ Igbomina ti nlo ṣugbọn nwọn sọ wi pe Ọlanrewaju ko si uile o ti lọ si Ipinlẹ Ariwa.

Igba meji ni a tun fi ẹrọ gbohungbo sọrọ si ile M. A. Ọlarewaju ni alẹ ana lati fun wa ni irohin ominira ilẹ Igbomina, ṣugbọn a ko le ri ba sọrọ lori ọrọ yi.

Bi a ba si ti tun gbọ ọrọ nipa ominira ilẹ Igbomina a si, ẹ o tun ma a gbọ ninu Iwe Irohin Imọlẹ.

# Awolọwọ Dorisa Apa 9

## Lati Ọwo Adio Mosanya

**Ko jẹ iyalẹnu pe ẹniti o ti ja ija akitiyan bayi yio ni ọta pupọ larin oṣelu; lẹna si ni awọn elegan yio pọ Babawa, ninu igbokegbodo yi, mo ti ri ọpọlọpọ ohun ayọ ati ibanujẹ ṣugbọn mo gba gbogbo rẹ pẹlu ọkan kan. Peteru kan (ki ṣe apostol Peteru ti inu Bibeli mimo) ninu iwe kan ti walpole ko ti anpe ni "Fortitude" sọ bayi pe:-"Igbesi aiye fun ara rẹ ko jẹ nkankan bikoṣe ọkan Akin ti a ba fi lo aiye na.**



**Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ati Iyaafin Rẹ**

Lẹhin igbati nkan buburu ti ba Peteru, o gbọ ohun kan ti o sọ fun pe:- Ibukun ni fun g b o g b o ibanujẹ rẹ, ki o si mu ọkan le lori iṣoro. Ibukun ni fun gbogbo nkan ti i sọ enia di ọkunrin"

Oluwa mi, gẹgẹbi ọrọ Peteru, emi na wi fun ọ pe! Ibukun ni fun idajọ rẹ; Ibukun si ni fun asiko ẹwọn ti o fẹ da fun mi.

Nisisiyi ki iṣe ti ara mi lo nja mi laiya bikoṣe pe ẹwọn ti o fẹ ju mi si yi le ba nkan pupọ jẹ fun ilẹ Naijiria. Idi mẹta pataki lo mu mi sọ eyi;

Ekini: Bi o ba ju mi si ẹwọn, ilu yi ko ni ri mi lo mọ fun iṣẹ ribiribi ti mo ti ṣe mo si tun le ṣe fun ogo ilẹ na.

Ereji: Gbogbo rudurudu ti o ti wa lati nkan bi Oṣu mẹdogun sẹhin le pọ si; o si le ko ba awọn ile miran ninu apapọ ilẹ ti a npe ni "Commonwealth."

Ẹkẹta: Fun igba diẹ si, iran eto ijọba alaṣaro ti a fun ẹnikọkan wa ni anfani lati ṣe bi o ti fẹ, ti o si gba ọrọ ofin gbọ, le yipada ki a si pada sinu o k u n k u n biribiri.

Ṣugbọn lẹhin okunkun biribiri imọlẹ yio de, Nitori na, pẹlu alfoya, idaniloju ati ireti ni mo fẹ kuro lati lọ sinu okunkun. Mo si ni igbekele ninu Oluwa pe ayọ mbọ l'owuro.

Awọn ọta mi le ma sọ pe kini Awolọwọ nfi ara rẹ pe? Bi mo ba ku nko Ṣugbọn iku ko ti pa mi; mo si wa l' aiye, mo wa l a i y e, B ẹ n i ng ko ni ku si ọgba ẹwọn.

Nitorina, o da mi loju pe anfani ki a r n ki a yan bi o ti wu wa eyiti a n i ki iwọ Oluwa adajọ ni dabobo yio si ma wa iti koja ẹwọn ati ide.

Mo fẹ sọ fun ọ loni pe ninu ile ẹjọ ti a wa yi, ninu apoti ẹj yi, mi i l ẹ Naijiria titun ti bere si wa s' aiye. Iru emi y i ni mo ti fi gb gbo ọjọ aiye mi ja fun lati ri pe ko parun.

Ki ng to pari ọrọ, mi, mo fẹ sọ pe pẹlu gbogbo idaduro fun ọsẹ diẹ to kọja ti ko jẹki o tete ṣe idajọ yi, mo ki ọ fun suru ti o ni nigbati a nṣe yi. Pataki julọ, mo dupẹ lọwọ rẹ fun iyesi ti o fun mi ati awọn ẹlẹgbẹ mi. Mo dupẹ o nisiyi mu ṣe tan lati gbọ idajọ rẹ"

Eyi ni ọrọ iwuri ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, sọ, Bi o si ti pari ọrọ rẹ ni adajọ Ṣuwẹmimọ bere ọrọ tirẹ. O sọ bayi pe:-

"Ohun ti o wu ki ẹlomiran le sọ, ero t' emi ni e'eyi o, Ki ṣe bi adajọ ni mo fẹ sọrọ bayi bikoṣe gẹgẹbi ọmọ Naijiria. Bi o ba ṣe pe iwọ nikan ni a mu wa siwaju mi fun ẹsun yi, ng ki ba ti ju ọ s,ẹwọn. Ṣugbọn ko si ohun ti mo le ṣe bayi nitoripe mo ti ju awọn ọmọ kekere wọnyi s'ẹwọn. Nitorina, mo ni lati fi wọ na s'ẹwọn pẹlu. Iwọ ti o ti jẹ ọkan n i n u awọn Olotu Ijọba ipinlẹ lo wa di ero apoti Ng ba sọ pe ki o ma lọ bi o ba ṣe pe iwọ nikan ni a mu wa siwaju m . Ng ba ro pe ṣeyi yyi ti ju rẹ ti ri te fun inra ẹjọ y nitoripe itiju nla ni o jẹ.

Ṣugbọn pataki ọrọ ẹjọ yi ti mo ti ri ti mo si gba, iba di ọpọlọpọ ibaje silẹ ati pe iba gba ọdun pupọ lati tun ṣe.

Gẹgẹbi mo ṣe ri oro na ni pe okan ninu awọn ti o parapo lati ko ile wa ngbero lati wo ile na. Ohun ti mo mu jade ninu ọrọ ni pe eni na fẹ yi oju awọn yoku sẹhin.

Ọkan ninu ohun ti o dun mi ni pe ọkan inu awọn ti o ja fun ominira ile yi eniti o ti se olotu Ijọba Ipinle olori Alataka Ijọba ni ile Igbimo Asofin ni Eko agbe joro tun wa ni idi nkan bayi evi l' o mu ki oro na ta koko.

Lehin igbati mo ti pinnu ati ju awọn ọmọ kekeke s' ewọn awọn ti mo pe mo iranse ni nwọn jẹ ni u oro ẹsu vi bi ba se pe bayi ni oro na ẹ ise mọni lati ri pe a i go awọ o ba jẹbi ẹsun ay o jẹ eyiti awon el m r o p m se ju sa u

e ba se iwo nikan ni a mu wa siwaju mi ba da o silẹ Abu u nl ni pe ti ara r s ran yi ṣugbọn ejo ọrọ iselu ni opolọp nkan miran wa i a ko ni ri di wọn l itai hun i mo ni ẹjọ ti o r ni aju m e ni o mu m so pe tanu na j e puọ ki se u adajọ ati da si ọrọ se

O so ipa idaduro i o w lori ẹjọ yi ki se be r ra i o b w ni ipo mi ni ti o si k die inu aw n nkan wo yi eri ti o gba eg eta oju iwe (800pages) oro awọn ag ej r a tun ba egbeta ej we (600pages) ati r sirisi a j y n u mi ba dun lati so pe ejọ na ti pari mo si ti da gbogbo awọ ti fi ẹsun kan sile o ya mi lara lati sẹ asise lat da eniti a fi ẹsun kan sile ju pe ki gb enia ju s' ẹwọn laisi idanloju ẹsun ti a fi kan.

Ohun ti o sele ni ibo mi ran ko kan mi ṣugbọn nigbaniran en a ni lati ro ọrọ ti o jẹ mo wọn.

Ng ko ri nkan rere ẹwọn le sẹ fun o ṣugbọn mo gba gbo pe iwo lo da gbogbo nkan wọnyi sile mo wipe ki sẹ i ara rẹ lo nja.


Ẹ DIBO Fun




Akukọ

# IWA RERE NI NKAN

Lati Ọwọ LATIFU BABALỌLA Akọwe Agba Ẹgbẹ IMỌLẸ AIYE

Ọmọ ti ko ni iwa rere ko ṣoro mọ nibikibi ti o ba wa Iwa aibikita ati tani yio mu mi, ti o ba nhu ni yio fi han gbangba iru ọmọ ti o jẹ ẹfin ni iwa ko se fi pamọ rara Bi ọmọ ti ko ni iwa ba ti ndasi ni iwakiwa yio tun bọ ma wọ lẹwu yio se bi ohun daradara ni on nṣe yio tubọ jingiri sinu iwakuwa apa ẹnikan ko ni le ka mọ awọn Yoruba lo ma npa owe kan bayi pe: kekere ni a ti pẹ kan iroko bi o dagba tan apa ko ni le mọ.

Idi ni eyi ti a fi nri ọpọ lọpọ ọmọ ti o ba dagba tan ti wọn ndi Ọmuti, ole Oju kokoro ati ẹlẹwọn paraku ohun pataki ti o yẹ ki a kiyesi ni pe iru iwa ti a ba ri kọ ara wa nigba ewe ni yio sọ 'i igbesi aiye olukuluku wa yio ti ri nigbati a ba dagba owe Yoruba kan ni o lọ bayi pe Yiyọ Orun ni sọ bi oju ọjọ yio ti ri.

Ọmọ ti ko ba ni iwa re re jẹ itiju fun awọn Obi rẹ Ib nujẹ ti o to iru rẹ fun Obi ko wọpọ sibẹsibẹ bi a ti ṣe itọju iwa ọmọ miran to ko ni gbọ ko sa ṣe ti inu rẹ sa.

Tani fẹ ki ọmọ bibi inu on ma ṣe wulo fun ọjọ aiye rẹ afi ki o ma a sunta ki o si ma wọ ẹwọn bi ọbọ awọn onilu ni o saba ma nṣọ bayi pe, Oba lowo lọwọ to sọkẹrẹ Iwa rere ni nkan.

Mo bẹ gbogbo ẹnyin ọmọde, papa gbogbo ẹnyin ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ẹ jẹ ki a ma hu iwa rere nitori iwa rere lo dara. i e lati nko ẹsọ re ode od[1] ọwọ wa Lọsẹ to mbọ, lagbara Oduduwa emi yio bagbo gbo ẹnyin Ọdọ sọrọ nipa ẹgbẹ ọdọ titun ti a npe ni Nigerian Youth Pioneers, ati itumọ pataki ti a le fun ẹgbẹ na pẹlu ero ẹgbẹ na fun awa Ọdọ ilẹ Naijiria nitorina ki ẹ tọju kọbọ meji yin silẹ.

# YẸ IRAWO RẸ WO

AQUARIUS (Jan 20 Feb 18) Ọjọ oni ko buru tobẹ ṣugbọn ọro nla kan yio ṣẹlẹ loni lori ohun kan Maṣe gbẹ kẹlẹ alejo rara Masi ṣe ba ẹnikẹni jowu papọ.

PISCES (Feb 19 - Mar 20) Ere nbẹ fun ọ loni ṣugbọn agbara rẹ ko bẹ ṣe suru, ki o ma si ṣe aṣeju ki o le dara fun ọ.

ARIES (Mar 21 - April 19) Fi oju ati ọkan rẹ si awọn nkan ti o nṣe pataki nikọn, ki o si ma feti si gbọran ki o to fesi si ọrọ, ṣugbọn jẹki ọgbọn ori pe daradara

TAURUS (April 20 - May 20) Ire nbẹ fun ọ loni Ẹyọ kan ti adun ni igbẹhin re Iwọ yio ri otitọ ọrọ gbọ lati ọdọ awọn enia pataki feti si imọran wọn.

GEMINI (May 21 - June 20) Arẹ yio mu ọ loni ṣugbọn odara fun ki o ba enia sọrọ pupọ ṣọra rẹ ki ori rẹ ma pa Ẹsẹ di ọwọ rẹ

CANCER (June 21 - July 20) Awọn ọrẹ rẹ a ọ ati awọn titun yio ni lọ tẹrun si ọ awọn obinrin yio si fẹ ọpọlọpọ ọrẹ atijọ yio sọ nkan iyanu si ọ.

LEO (July 23 - Aug 22 Gbogbo arisiki rẹ dabi eyiti o tilọ sibẹ bo tilẹ jẹ pe igba ko lọ bi orere fun ọ o ko ṣai si o kuta idigbolu ọpa rẹ maṣe gbẹkẹle ẹnikan tabi alejo.

VIRGO (Aug 23 - Sept 23) O dara ki o tete wa wọrọ kọ fi ṣe ad masi ṣe ko ohun ti o ma da bẹ ni ki o maṣe atako si ọrọ ẹnikan ki wọn ma mu ọ ni ọta.

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Ọkan rẹ ko ni balẹ loni ki o ma si ṣe jẹki ibinu bori ọgan ko ṣe alaisi iṣoro diẹ ọgbọn ori rẹ ko si to ṣugbọn Iwọ yio gbọ Irohin ayọ.

SCORPIO Oct 22 - Nov 22) Ire nbẹ fun ọ lọjọ oni kole ṣe ki o maṣe si iṣubu ati idi ẹ fun nipa owu jijẹ gbo gbo rẹ yio ma ṣiṣe pọ fun rere.

SAGITTARIUS) Nov 23 - Dec 21) Iṣọrọ kan pẹlu igbo ara kan yio ṣẹlẹ larin iwọ pẹlu ẹnikan ninu awọn ẹbi re mura lati ṣe atunṣe.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 19) Awọn ọre rẹ atijọ ati awọn titun yio jẹri ọjọ oni ṣunwọn fun ọ ki o si gba mọran nipa bi aṣe ntọja owo nipa iṣẹ


## KẸRẸ O!

Kurani Ọgbọn Eṣu ti a ṣe Larubawa ati itumọ rẹ lede Yoruba 25/- Postage 1/6d, Iwe Adura pataki fun Ariski ati iṣẹgun lori ohun gbogbo lati ilẹ Misira 1/6 Iwe Atumọ Ala ati Adura Ala ibajẹ ti a ti nta ni 4/- o ti din si 2/6d Afọmọ isin Mohammed 1/—

Tete ra tirẹ lọdọ:—

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue, Lagos Nigeria
( Leti Ọja Jankara l'Eko



## Kini E Nduro Fun ?

Bi o ba ni aṣọ fun fifọ ati lilọ bi ( wollen ) aṣọ oke, Tapeta Sapẹti ati oriṣiriṣi aṣọ ti o ba ni fun fifọ ati lilọ ni iṣẹju kan

TETE GBE WA SI ỌDỌ
**JOYCE LAUNDRETTE SERVICE**
34, Ojo — Oniyun Street,
Apapa Road Ebute Mẹtta

Kia ni ao ba ọ fọ ti o si ri gba ni ẹsẹ kanna. A ṣe wa gba ni ile rẹ, ki a si ko pada fun ọ ti a ba fọ tan kọ nomba ile rẹ ranṣẹ si wa.
Dan wa wo lẹkansoso ki o si ri bi iṣẹ wa ti dara to owo pọọku ni a si ngba



GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIK

ALE-BI-ALE Egbogi Toniki Jamanu titun ti gbogbo ara ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala ṣiṣe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ko ba ṣiṣẹ daradara ti Eemi Breath) inu rẹ ko ba gunlẹ daradara fun iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo' tabi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ogbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mọ daju pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ'ara rẹ di ọtun pa tapata ara rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ tio ti hunjọ yio yi po pada patapata alafia ati gbadun yio de si ọ Iyen bẹ

Bere egbogi na ni Ṣọbu:

NIGERIAN MEDICENE STORES
4, Tinubu Square Lagos
Waterloo Medicine Stores,
8, Palm Church Street, (Ọja Ita Faji
Lagos, Nigeria.
ADEDUN CHEMIST
14 Wakeman Street Yaba

EGBOGI AWỌN ARA ILU FARANSE

# TESSYDRE

Fun Ọmọ — Ọwọ Ati Ọmọde Gbogbo



Tessydre jẹ ojulowo egbogi haunhaun ti mejẹ i rufẹ rẹ kosi kakiri igboro ilu Nigeria fun itoju ọmọ ọwọ tabi ọmọde lati le jẹ ki wọn ma hu EHIN ẹnu wọn pẹlu irọrun laisi wahala rara tabi aikole sun yala losan tabi sun awọn iya wọn gbogbo Ogorun orisirisi egbogi bayi ni wọn npolowo sinu ero gbohungbohun ati sinu iwe kika lojojumọ sugbọn kosi eyi ta le fi we egbogi Tessydre rara o. Ọlọgbọn di ori ẹja m... pupọ ni o u awọn ara ilu Saro ati awọn ara ilu A... ...nyin (CHANA) mọ egbogi yi dajudaju on na ni ... ba ṣẹṣẹ bi titi fi di ... wọn si nlo fun awọn ọmọ ti wọn wahala tabi ... akọn bi ome ọdun wawa gbako. Kosi fẹkun fẹk... ọnu inu rirun ọka ori inu iwọ aiperi osinnu ṣiṣu ... un ewo, kokoro ara lapalapa ara gbigbona igbẹ i... gburu tabi aikolokun ninu ara sisu, Inu kunkun iro af fẹfẹ ati oriṣiriṣi awọn amodi tabi aisan ti o ma nyọ awọn ọmọ ọwọ lẹnu ni ba Ehin HIHU" gbogbo. Tessydre a ma mu ki ehin ẹnu rẹ ọmọ rẹ lagbara gidigidi ati Isan ara wọn pẹlu.

Awọn ọmọ ti wọn nlo egbogi yi ki saba ṣe ... m i rara niwọn igba ti wọn ba ti ngbọse dede, ti otutu ko si le ri aye lati duro ni igbay... wọn ti wọn jẹun ... ara dara ti nwọn si nsun gbadun pẹlu

Bere Egbogi Ni Ṣọbu Awọn:—

WATERLOO STORES
8, Palm Church Street, Lagos
ADEDUN CHEMIST
4, Wakeman Street, Yaba

**Ipolowo Ọja Rẹ Ko Ti Yege**

*Nitoripe*

O KO TI POLOWO OJA RẸ SINU

**IROHIN IMOLE**

T'ODUN KA FUN GBOGBO YORUBA

KOWE IPOLOWO OJA RẸ SI
ADVERTISMENT MANAGER

**IROHIN IMOLE**

16, Famglọse Street Phone 2 9 5

# ÌWE SI OLOTU

## Isẹyin Kọ Ẹgbẹ Dẹmọ

*Olotu*, Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin oloyinmọmọ lati fi han gbogbo awọn ọmọ ilẹ Yoruba pe awọn ọmọ ilu Isẹyin ko ṣe ẹgbẹ Dẹmọ rara ati pe lojọkọjọ ẹgbẹ Afẹnifẹre eyi ti Oloye Awolọwọ nṣe olori re ni ti awọn ọmọ ilu Isẹyin Mo fẹ fi ye ẹnyin enia to ngbọ pe awọn ẹgbẹ Dẹmọ ma nwa si Isẹyin lati ṣe eto ipolowo ibo

Ṣugbọn mo fẹ fi ye nyin pe ko si ọ m ọ ilu Isẹyin to le gbagbe iṣẹ ti Oloye Awolọwọ se si ilu Isẹyin ati agbegbe rẹ lasiko ti o wa lori aga gẹgẹbi Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria. Lati igbati gbogbo nkan ti kuro lọwọ Oloye Awolọwọ ni a ko ti ri nkan



OLOYE S.L. AKINTỌLA
Olori Ẹgbẹ Dẹmọ

to jẹ rere kan ni ilu Isẹyin a fi pe ẹgbẹ Dẹmọ ma fi iya ma jẹ awọn enia ti ko ba ṣe ti wọn. Ntori eyi a kọ ẹhin si ẹgbẹ Dẹmọ patapata, Olotu mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
Jimọh Adesọla
ISẸYIN.

## Agege Nfẹ Itoju Ijoba

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin Oloyinmọmọ lati kesi Olotu Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lori eto to jẹ pe ilu Agege ku eyi to jẹ pe ilu na ko si kere ninu awọn ilu to wa ni ẹkun Ikẹja ati pe a ko fi owo ori wa njafara rara.

Inu awọn enia Agege yio dun bi Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ba le tete se mojuto ilu yi lati ri gẹgẹbi ilu na ti ri ati awọn nkan to jẹ alebu to wa ni ilu na eyi ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ko si gẹgẹbi ilọsiwaju yio se wa ni ilu na.

Eleyi yio si dara bi Olotu Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ba le lo ipo rẹ rere la ti ba wa se eto bi idagbaso ke yio se wa ni ilu Agege lati le jẹ ki a jẹ anfani owo ori ti a nsan si apo Ijọba wa na. Olotu mo dupẹ pupọ ọkọ Ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ. Amin.

Emi ni
Alice Adebisi
AGEGE

## A Nfẹ Irohin Imọlẹ Ni Ilu Ọffa

Olotu jọwọ gba mi ni aye dẹ ninu iwe nyin oloyinmọmọ lati fi alaye mi yi ye nyin ni ẹkun rere lori iwe nyin Irohin-Imọlẹ eyi to jẹ pe a ko nri ka ni ilu Ọffa a fi ti awọn enia wa to ba wa ni ilu Eko tabi Ibadan ba wa si ile ni a ma nri iwe na ka eyi to jẹ pe irohin aladun ati awọn itan to fa ọgbọn wa o si kun inu iwe na.

Eleyi yio si dun mọ awọn ọmọ ilu Offa ti ẹ ba le lo ipo nyin rere ki ẹ ṣe iranlọwọ fun wa gẹgẹbi a o ṣe le ma ri iwe Irohin Imọlẹ ni ilu Offa gẹgẹbi ilu miran ni ilẹ karọ o jire bi? Nigbati mo ri iwe na o jẹ ohun to ya mi lẹnu lati ri pe iwe irohin kan wa lede Yoruba eyi to jẹ pe ojojumọ lo njade.

Inu wa yio dun bi a ba le ri iwe na ma ka ni ilu Ọffa ni ojojumọ ati pe ki ẹ tete ṣe eto bi ẹ se ni Asoju kan ni ilu Ọffa. Olotu a nreti nyin.

Emi ni,
Adetoye Balogun
OFFA.

Ẹ Ma a Ka Iwe Irohin Imolẹ Lojojumo Ki ẹ Si Ma a Polowo Ọja Nyin Sinu Rẹ Pẹlu

# Yoruba Ko Gbọdọ Gbagbe Ore Ti Awolọwọ Ṣe Silẹ

Ẹyin ena mi ti ẹ jẹ ọmọ ilẹ Ijẹbu jakejado ilẹ Naijiria paapa julọ ni ilẹ Yoruba mo ro pe ' o si .nikan to gbodo gb.g'e ore ula ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ṣe si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni akotan lasiko ti o wa gẹgẹbi Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati paapa ni asiko ti o jẹ pe ẹgbẹ rẹ ti o jẹ ẹgbẹ Afẹ ifẹre lo nṣe akoso Ijọba Ipinlẹ na

## Lati Owo Olujoye Tiamiyu



Oloye Awolọwọ

Ti a ba nsọ iru ore ti oloye Awolọwọ ṣe si ipinlẹ Iwọ Orun a ko le sọ tan ni oṣu mẹfa ati pe awọn agbẹ ilẹ Yoruba ko gbọdọ gba rẹ ati awọn agbẹ jakejado ilẹ Naijiria lori owo koko ti o jẹ ki o ga soke ni ipinlẹ Iwọ Orun eyi to je pe o ran awọn agbẹ to wa ni ilẹ Naijiria lọwọ.

Ti a ba tun mu ẹnu kuro nipa ti awọn agbẹ awọn ọmọ to jẹ pe iranlọwọ oloyẹ Awolọwọ lo gbe nwọn de ipo giga loni lori eto ẹkọ ati pe awọn obi ọmọ miran ko ni agbara lati ran ọmọ rẹ ni ile ẹkọ si jẹ pe o ri anfani eto ẹkọ ọfẹ jẹ ti awọn ọmọ wọn si wa ni i p o giga ai ọjọ oni nitori eyi ẹnyin enia mi si fẹ ki ẹ lọ o iru ore ti ẹ le ṣe lati fi san ore fun Oloye Awolọwọ.

Otitọ ni a ngbọ a r i w o kakiri ti nwọn n k e g b e Awo ! Awo !! Awo!!! ṣugbọn ki ntk le mọ pe otitọ ni awọn enia wọnyi fẹran Oloye Awolọwọ o di ọjọ idibo ki nio le mọ pe awọn enia wọnyi f ẹ r a n Oloye Awolọwọ de inu ati pe ki nwọn si fi ibo gbe jade.

Nkan ti mo fẹ so le ti awọn Ijẹbu loni yi ni pẹ awọn Ijẹbu a lọ s opa lowe pe ' Ijẹbu ki jẹ ọjọ" Ṣ u g b ọ n mo si mọ pe ti ọmọ an b i a ti o jẹ ọmọ ọkọ Ijẹbu ti ko ba d i b o fun ẹ g b ẹ Afẹnifẹre eleyi yi fi han pe O w rẹ ko mọ ore patapata

Nitori m i pe ọpọ'ọpọ ilọsiwaju ti gbogbo agbegbe Ijebu ni l siko ti ẹgbẹ Afenifere fi nṣe akoso Ijọba ipinle Iwọ Orun ki iṣe kekere papa ni ilu w ọ n y i Abeokuta, Eki ati agbegbe Oshun ti awọn ilu ti mo darukọ re yi ko ni fi iwa al aimọ ore ra nṣe lo ye ki ọmọ ẹgbẹ ti yatọ si ẹ g b ẹ UPGA padanu owo ibo rẹ nigbati nwọn ba nka abayọ ori.

Ẹyin ọmọ ilẹ Ijẹbu nile ati loko mo ro pe ilu miran ti ko ju oju mẹdoguu lo si je pe nwọn ngba ro aṣorọmagbesi ti nwọn da ọda si ọja ọoa wọn ti awọn ilu nla miran ni omi ẹrọ pẹlu ina ẹlẹntriki. Nitori eyi ẹyi n en a mi ile ẹjọ to ku payi lati jẹ pe a le da Oloye Awolọwọ lare bayi ni eto yi ki ẹ si jẹ ki a fi tọkantọkan dibo wa fun ki a si le fi ibo wa da a lare.

Nitori eyi ohun to jẹ pe o le se anfani fun wa lẹhin ọla ni ki a ro ti awọn ọmọ wa to wa lẹhin ati awọn t nwọ ko bi rara i a ma tori ifẹ owo ki a gbe ile Baba wa ta ki ẹ jẹki a kọwọ awọn ọd lẹ silẹ ki a ro igbe si aiye awọn ọmọ wa ki a si dibo fun ẹgbẹ alakukọ ati ẹgbẹ Afẹnifẹre ki ilọsi aju ati alafia pẹlu Ijọba rere yio ele tẹ wa lọwọ tabi pe ki ae si le ri ọwọ na gẹgẹbi d ti wa tẹle ṣugbọn ohun to le fa le eyi wa ni pe ki o dibo wa fu ẹgbẹ olọne ilu eyi ti ise UPGA i Awolowọ le jade lati wa fun wa ni ọna eto ti yio mu ọgbọn ati ilọsiwaju ba wa o di gba die.



Alhaji D S Adegbenro


Ẹ Dibo Fun



Ọpẹ



**Gbanjo ! Gbanjo**

FUN ỌDUN KERESIMESI

A ni lati fi kede fun awọn onibara wa pe Ọja gbanjo wa bẹrẹ lati oni lọ titi di 30/11/64. Tete ra tirẹ ki o to kasẹ nilẹ

APEJUWE ILE ITA IWE WA

Wọ Bọọsi Mushin, sọkalẹ ni Atẹwọlara Bus Stop ! Bere ladipọ Street, ti o ba rin titi Ladipọ, bere ILE IWE ODU - ABỌRẸ. Ti o ba de ibẹ tan, wa be re Nomba 5, Alaba Stree Mushin, ile iṣẹ wa dojukọti ODUS SURF"

AWỌN ỌJA WA

Olubori Egbogi Ajẹbidan 40s di 30s Iwe Egbogi Ajẹbidan 25s di 22s Iwe Egbogi Awogba Aruu 20s di 17s Iwe Ilana Ifa purin titẹ ati etu ṣiṣe 20s di 17s Iwe Afoṣẹ Isẹdalẹ Yoruba ati Psalmu Ajẹbidan 3/6 di 2s 6d Turari Isẹgun Ajẹ 10s 6d di 8s Turari Itaja 10s di 6d 8s Turari Ala rere 10s 6d di 8s Iye owo Turari pangolo niti oke yi Turari ti o wa ninu pakẹti jẹ 2s 6d pere Iwe Itumọ Ala Joseph Alala 5s Iwe Aniyan eto Irun o ti di 2s 6d Akọnni lẹsin pataki Islam 2s 6d Tailor's Measurement book di 1s 6d

Tenants Agreement Forms 10/6d di 5/ Gold Smith Form.s
Certficate of Apprenticeship (mẹta) 17/6 di 10/6d

ỌJA TITUN TI A ṢẸṢẸ RI GBA

Abẹla mimọ fun adura tete Idaloju (orișiriși awọ pẹlu Turari.
Abẹla mimọ fuu itaja (Kowo wọle pẹlu Turari 20/-
" " " Iṣegun Ajẹ pẹlu Turari 20/-
Lọfinda tabi Ororo ipara fun itaja, Iṣẹgun Ajẹ ati arisikl 30/- Igo kan

Fi owo ranṣẹ tabi ki o wa ra ni ọdọ:—

J. O. Shoyinka
Alaba Street
5. MUSHIN.

# IROHIN IMỌLẸ

*IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA*

No 872 TUESDAY DECEMBER 15, 1964 [2D)

## Awon Ọmo Ogun Ilẹ Naijiria Lo Si 1jẹbu-ode

**IJẸBU-ODE** Ni kutukutu owurọ ọjọ Aiku ti işe kẹtala oşu yi ni awọn ọ m ọ ogun ilẹ Naijiria eyi ti a npe ni "Fourth Battalion of Naijiria Army" ni irohin fi ye wa pe nwọn wa ni ilu Ijẹbu-Ode bayi lori irin ajo wọn lati lọ fi ye awọn enia ilu Ijẹbu-ode lori gẹgẹbi nwọn le şe gbinyanju lati le lọ kọ işẹ ogun eyi ti nwọn yio fi odindi ọjọ mẹta şe ere eyi ti yio wu enia lori lati le lọ kọ işẹ ogun.

Awọn ọmọ ogun I l ẹ Naijiria na ni oniwe irohin wa ti i l u Ijẹbu-Ode fi ye wa pe ọ g a agba ti "Fourth Battalion Naijiria Army" ọga o g u n S. A Wali ni o şe olori awọn ọ m ọ ogun na lọ si ilu Ijẹbu-ode.

Irohin fi ye wa pe lẹba ile awọn ọlọpa ilẹ Naijiria ni Ijebu-Ode ni awọn ọ m ọ ogun na si fi şe ibudo Ni ana ni irohin fi ye wa pe awọn ọlọpa na şe orişirişi ere idaraya ni papa ti Itoro ni ilu Ijẹbu-Ode lati fi han nwọn e n i a lori awọn anfani to wa ninu işẹ o g u n ni ilẹ Naijiria ati gẹgẹbi olukuluku le şe gbinyanju lati lọ fun şẹ ogun.

# IYAAFIN AKERELE JARE ẸJỌ

**EKO:- Ni ojo Abamẹta ti işe ojo kejila oşu yi ni adajo Agba Ile ẹjo kekere Eko, Ọgbẹ ni Aı boola Ọlaloye paşẹ pe, ki 1yaafin Boye Akerele oka n ninu awon Aşiwaju ẹgbẹ Dẹmo l'Eko ati awon enia mokandin ogun pẹlu rẹ ki o ma a lọ layo ati alafia nitoripe ẹsun t a fi sun won ko fẹsẹmulẹ to**

Ọlọpa ti o ba Iyaafin Akerele ati awọn yoku rẹ şe ẹjọ şe alaye fun ile ẹjọ pe, ni ọjọ kẹwa oşu kọkan la Ọdun yi, ni rogbodiyan ti o fẹrẹ di ija igboro bẹ silẹ ni opopo Şhẹtẹolu Eko

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ọlọpa sure de ti nwọn si dekun ija na ti nwọn si mu awọn ti nwọn da ija na silẹ lọsi Teşan awọn Ọlọpa lati gbọ ti ẹnu wọn.

### ALAYE

Ninu idaje rẹ eyiti, o şe fun işẹju mẹdogun, Adajọ na şe alaye pe ẹgbẹ oşelu kan ko le ma a ba ara rẹ ja laiko si ẹgbẹ oşelu keji gẹgẹ bi alaye ati ẹsun ti awọn Ọlọpa mu awọn enia na wa si Ile ẹjọ fun.

Adajọ na tun şọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe' on gbagbo wipe otitọ ni Iyaafin Akerele mu ẹgba, ti o si fi na awọn ọmọ Ile iwe ti nwọn nkọrin owe ati ọtẹ niwaju ile rẹ ni ọjọ na.

O ni awọn ọlọpa ti kuna ninu işẹ wọn, nigbati nwọn ko ti le mu awọn ọmọ Ile Iwe na wa si ile ẹjọ ti o wa jẹ wipe Iyaafin Akerele nikan ni awọ ọlọpa mu wa gẹgẹbi arufin Adajọ na wa bere pe, A gbọ wipe enia meji ja ẹnikan lara, ẹnikeji dn?

Adajọ na tun sọ pẹlu i anu pe, "ọna ti awọn ọlọpa gba ti o fi jẹ wipe, nigbati Iyaafin Akerele lọ ke si wọn ni "Lion Building" ti nwọn ko tete daa lohun ko jẹ eyiti o dara to rara!!

Osi ba awọn ọlọpa wi wipe, nwọn ko şe isẹ wọn gẹgẹ bi isẹ.

Adajọ na gba wipe, abani rojọ Ijọba na kuna ninu ẹjọ ti o ro, laiko mu awọn enia ẹgbẹ keji wa si ile ẹjọ lẹhinna o gba wipe Iyaafin Boye Akerele ọmọ rẹ ọkunrin Akinọla, Iyaafin Olufuntọ Thompson ati awọn enia mejidinlogun minran ti awọn ọlọpa mu, ko jẹbi ẹyin na ı itori idi eyi, Mo da nyin silẹ, ẹ ma a lọ ni ayọ ati alafia.


## IDIJE ! IDIJE.

A fi eyi kede fun awọn Onkawe Irohin Imọlẹ ati awọn Ọmọ karọ-o-jire pe a nfẹ

## ITAN L'EDE YORUBA

Eyiti ẹnikẹni ko ti tẹ jade ninu iwe ri tabi ti nwọn ko ti sọ lori ẹrọ Redio ri Ẹnikẹni ti o ba si bori yio gba

**(£5)** PỌNUN MARUN

Akiyesi;- Kọ itan tirẹ ki o han rekete, ti ẹniti ko ba han a o fa ya ni, ki o si mọ dajudaju pe ko ni ipa ninu Idije na, ITAN ẹniti o ba si daraju ni a o tẹ jade ninu Iwe Irohin Imọlẹ yi a o si fi lọ(£5) Postal (Order) ranşẹ si

Fi Stamp Tọrọ (3d) ranşẹ fun gbigbe Pọnun marun (£5) ti o ba jẹ pada si ọ. Ki o ge ibiti Idije yi wa, ki o si fi ranşẹ pẹlu Stamp tọrọ rẹ si wa. Ẹnikẹni ti ko ba ge Idije tirẹ ranşẹ siwa ti o ba jẹ owo na a ko ni fi ranşẹ si.

Orukọ............................................................

Ibugbe............................................................

..................................................................

Fi itan rẹ ranşẹ si:-

**Olotu Irohin Imọlẹ**
16, BAMGBOSE STREET, LAGOS.



## Congreves Female Remedy

(FUN OBINRIN

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin t o ba ni iyọnu abi amo di inu rirun nigbakugba ta i n ẹkọ ọkan ẹhin didun ibadi wiwo tabi sisan ẹjẹduu ati tabi aikoto ẹjẹ ara Inu gbigbona nigbakugbo Igba- -aiye riro ọmu riro didun arẹ atinu wa ni o ma nfa oyi-oju Ilaogun a a ẹşẹ ara sisan ẹfọri tabi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itoju gbogbo Obinrin gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orişirişi amodi miran ti o ma ayọ wọn lẹnu ni iru nigbakugba pẹlu

NIGERIAN MEDICINE STORS
4 Tinubu Square Lagos

WATER-LOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone :- 22678 Nigeria, (Ọja Ita faji

ATI NI ŞỌBU
OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN.


Printed And Published by Modupẹ Printing Press. 16 Bamgboşe Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADELỌSUN 45, Campbell Street Lagos (15/12/64)